# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,692 TUESDAY, FEBRUARY 8 1966 (2D)


## Okunrin Kan Şeeşi Ko S'ęnu Mọto

ASABA:- Ninu irohin kan to de ọwọ wa lati ilu Asaba ni a ti gbo wire mọto pa ọmọ kunrin ti işe ọmọ ọdun medogun eyiti o je pe gẹgẹbi ọmọ na ti nbọ lati inu igbo ti o si jade si oju ọna ni ọmọ na ti o je ọmọ ile ọkọ şeeşi ko nu mọto akero kan to nbọ loju ọna na ti ọmọ na nfẹ pada sile lati inu igbo.

Onlwe irohin wa ni ilu Asaba fi ye wa ninu irohin re pe lẹhin ti awọn ọlọpa de ibiti işẹlẹ na ti şẹlẹ ni nwon to mọ orukọ ọmọ kunrin na ti nwọn npe ni Okafor Okonkwo ti o ngbe ni nọmba 17, Ogbilo Street, Asaba Irohin awọn Ọlọpa na tun fi ye wa pe ọmọ kunrin na nbọ lati inu igbo nibiti o ti lọ şe igi eyiti o je wipe bi ọmọ kunrin na ti nbọ ni mọto na lọ kọlu ọmọ kunrin na ti o si pa ọmọ na patapata.

Awọn Şọja to lọ sibi ti işẹlẹ na tun fi ye oniwe irohin wa pe ọmọ kunrin na Okafoe Okonkwu npadabọ lati inu igbo nibiti o ti lọ şe igi eyiti ọmọ kunrin na nfẹ koja lati oju ọna na ti ko si wo odikeji ki o to sọda lati oju ọna eyiti mọto akero na si pa ọmọ na patapata. Lẹsẹkẹsẹ na ni awọn ọlọpa ti yara gbe oku ọmọ kunrin na ọ si ile iwosan ti ilu Asaba lati lọ şe ayẹyẹ rẹ ninu ile iwosan lakulaku.

# IJỌBA OLOGUN FẸ KỌ ILE FUN AWỌN OŞIŞẸ

EKO.— Ninu irohin kan to jade lati ọwọ Ijọba Ologun ilẹ Naijiria ni irohin na ti fi ye wa pe Ijọba Ologun to nşe eto akoso Ijọba ilẹ Naijiria ti şe eto bayi lati kọ ile fun awọn oşişẹ ati pe nigbati Ijọba Ologun ilẹ Naijiria ba kọ ile na ti gbogbo rẹ yio jẹ ọgọta ni awọn oşişẹ ti nwọn ngba owo ti ko pọ lọju yio maa gbe eyiti yio tun jẹ irọrun fun awọn oşişẹ orilẹ ede Naijiria.

Irohin na tun fi ye wa pe Ijọba Ologun orilẹ ede yi ti şe eto lori ilẹ kan ti wọn yio kọ ile na si ni Surulere Irohin na tun şe afikun pe gbogbo ile ti Ijọba Ologun yio kọ fun awọn oşişẹ towa ni ilu Eko ati agbegbe eyiti awọn ile na yio jẹ ọgọta ati awọn oşişẹ ti ile na yio gba jẹ ọgọta le ni ẹdẹgbẹrun ọdun 960) ati pe ninu ile kọọkan ni yio ni awọn yara mẹrindinlogun ti o jẹ wipe awọn oşişẹ yio fi maa gbe.

Ninu irohin lati ile işẹ Minista Alamoju eto ile wiwọn ati ile gbigbe ni nwon ti şe alaye pe eto ti Ijọba Ologun ti lele yi jẹ apẹrẹ rere ati ohunti yio wu awọn oşişẹ lori.

Irohin lati ile işẹ Minista fun eto ile gbigbe na tun şe alaye pe anfani nla ti awọn oşişẹ ni ninu ile ti nwọn yio kọ fun wọn na ni pe ti olukuluku ba le ti bọ sinu ile na ni yio ni anfani lati ti ilẹkun rẹ nu ọna tirẹ eyiti o jẹ pe ko si papọ mọ awọn ol gbe inu ile kanna.

Irohin na tun fi ye wa pe ohunti o mu ki Ijọba Ologun tete şe eto yi fun awọn oşişẹ ilẹ Naijiria ni eto tabi ilero ti Ijọba Ologun na ti şe kede pe awọn gba eto akoso Ijọba Ijọba lọwọ awọn oşişẹ eyiti Ijọba Ologun na ti şe ileri ninu eto ijiana ti nwọn ti şe silẹ lati le ri pe nwọn şe eto lori ilẹ gbigba fun awọn oşişẹ eyiti nwọn yio ma san owo pọku ti yio tun mu irọrun wa fun awọn oşişẹ orilede yi.

Irohin na tun şe afikun pe lati igba ti awọn ọmọ Ogun ilẹ Naijiria ti gba eto akoso Ijọba orilẹ ede Naijiria ni awọn ti şe eto lati le ri pe irọrun wa fun awọn oşişẹ orilẹ ede yi ni pa ile gbigbe eyiti nwọn yio ma san owo pọku le ile ti nwọn yio ma gbe eyi ti yio jẹ pe Ijọba ni yio kọ ile na fun awọn oşişẹ orilẹ ede Naijiria,

Eto nipa ile ti awọn oşişẹ orilẹ ede yi yio ma gbe ni si jẹ aşaro kan ti awọn Ijọba Ologun ilẹ Naijiria şe pẹlu awọn Igbimọ kan şe ninu ipade kan ti awọn Igbimọ na pẹlu Ijọba Ologun ilẹ Naijiria nipa eto ile gbigbe fun awọn oşişẹ.

Bakanna ni irohin na tun fiye wa pe lati igba ti awọn ọmọ Ogun ilẹ Naijiria ti gba Ijọba ilẹ Naijiria ni nwọn ti mu eto ba eto ilẹ gbigbe fun awọn oşişẹ eyiti yio jẹ owo pọku ati eto lori awọn ile gbigbe larin ilu Eko eyiti nwọn yio din owo ile gbigbe ku fun awọn to ngbe ile ni ilu Eko.

Irohin lati ọwọ Ijọba Ologun ilẹ Naijiria tun fi yewa pe lati igba ti Ijọba Ologun ti gba eto akoso Ijọba ilẹ Naijiria ni awọn ile eto iroren ti ntọka si eto lori ile gbigbe eyiti awọn Ijọba Ologun na si ti ni ero rẹ lọkan lati şe.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe eto nipa ile gbigbe ni ilu Eko ati lati din owo ile ku ni o ti jẹ ohunti ile işẹ Minista Alamojuto eto ile gbigbe ati ile wiwon fun apapo Ijọba ilẹ Naijiria ti ni ero rẹ lọkan lati şe

Nipa eto eyi ni Ijọba şe eto ilẹ nla kan silẹ eyiti gbogbo ilẹ na si jẹ (63 acres) ti o si jẹ wipe ibiti o ba oju mu ni ile ti Ijọba yio kọ awọn ile na si ni Suru Lere,

Ile işẹ Minista Alamojuto eto ile gbigbe na fun Ijọba Ologun tun şe alaye pe ninu awọn ilẹ ti nwọn yio kọ awọn ile na si ni o jẹ wipe o ti fẹrẹ pari ati pe awọn ile to jẹ wipe o ti san oko rẹ ni irohin fi ye wa pa nisisiyi ni nwọn yio bẹrẹ lati ma kọ awọn ile ti Ijọba yio kọ sibẹ ati pe awọn ilẹ ti Ijọba yio kọ sibọ ati pe awọn ilẹ ti o jẹ wipe nwọn ko ti pari rẹ ni nwọn yio ma ba eto bi nwọn yio şe tun ma lo bayi,

Irohin na tun fi ye wa pe owo si ti wa nilẹ eyiti nwọn yio fi kọ awọn ile ti awọn oşişẹ na yio gbe si ti wa nilẹ lati le fi ma ba işẹ na lọ bayi.

Irohin lati ọwọ Ijọba Ologun ilẹ Naijiria na tun fi ye wa pe eto ti Ijọba Ologun ati awọn Igbimọ kan nipa eto ile gbigbe yi se ni ipade ti nwọn şe ni eto ile bi nwọn yio şe kọ ile na eyiti yio fi jẹ pe

WO OJU EWE KẸFA

## Ọga'gun Ayub-Khan Di Alakoso Ijọba



PAKISTAN:- Lẹnulọlọyi ni Ọgbẹni A. R. Cernelius olori gbogbo awọn Adajọ orilẹ ede ilẹ Pakistan şe ibura fun Ọga'gun Ayub-Khan Alakoso Orilẹ ede ilẹ Pakistan lẹhin ibo ti wọn di kọja lọ yi.

Ọgagun Ayub Khan lo wa ni ọwọ ọtun ninu aworan oke iwe yi nigbati ọlọla A. R Cernelius adajọ agba ẹniti o duro ni ọwọ osi nse ibura fun olori Ijọba Ayub Khan

# AWỌN IWA IBAJẸ TI O WA NI ILE — AIYE

## Lati Ọwọ Ẹfufu - Lẹlẹ

**Emi Ẹfufu lẹlẹ nki nyin o, Ẹ ku owuro, eku iyalẹta, e ku gbogbo asiko yi. Ṣe asiko yi ko gbo nyin bay? ṣe inu nyin dun, se erin muse yo lerekẹ nyin tabi b wo ni aiye nyin ti ṣe ndun s? Dajudaju mo mo pe elomiran y o dahun pe awon gbadun ati pe aye tuntun ti de fun awon Ba anna awon elomiran yio ma ro r run eh n pe awọn ko ma gbadun ni d won, Beni mo gi a f n laye awọn ero meje ji yi.**


# KERE O

ẸNYIN ỌMỌ ODUDUWA

"ỌBA ATERERE KAIYE NI NYIN" PELU ỌPỌ AJASEGUN RE



**Ọba Alaiyeluwa Oduduwa**

Ẹ ku ọdun Ẹ ku Ajaṣẹgun, Ti ko ni le nyin, Ọna ko ni na nyin, Ajinde ara yio ma je fun nyin.

Ẹ mura lati di opo Ado Osogun Aeuiyi Ironsi mu, Eni to tun ilu te bi eni Te'fi, on Io T'ai ero bi Agnzo, O le ọta lagbo, O le oṣi danu, o fi Naijiria lokan bale.

Niẹ o ti ra n'nu itan Igbesi aiye Oduduwa ati ti awon ọmọ rẹ?

Maṣe jẹ ki nwọn wa rohin re fun o, "Kose mani" ni kan inu iwe na je fun Omo Yoruba. Tete lo ra tirẹ toto tan 3/- pere ni, Postage 9d

Fọwọ tirẹ ranṣẹ si.—

ẸSAN KOGBOGBO SERVICE
8 Iduma Ikorodu Avenue Lagos Nigeria.
Leti oja Ido ara


Emi Ẹfufu lẹlẹ ti mọ ero awọn omọ enia wọnyi pe isoro wa ni o a awọn opo enia, h n o han si emi Ẹfufu lẹlẹ ni pe b' Ii ba Ologun wa tabi ko si ẹn ti ebi pa a m k gbe soke fun a ni.

Nitorina emi Ẹfufu lẹlẹ ni oh n pupọ lati ba won so sugbọn ọkan nyin ko le gba won, nitori awọn ti a pa enia won larin rogbodiyan to koja pọ pupọ nigbati awọn Ologun gba ijọba lọwọ awọn oselu na tun wa bi ehun ẹdun, lẹkun wọn. Gbogbo awọn ẹ'ẹ a'aiṣe wọnyi lo wa siwaju Oluwa.

Iṣan ẹiẹ n pọ tobẹ ge ti Oluwa ni ki wa si a r i n awọn ọmọ enia lati ran won leti awọn iṣẹ ti a ran emi Ẹfufu lele si won ni nkan wọnyi bi ọdun to koja

Nje e ranti awọn Iṣipaya Emi Ẹfufu Lẹlẹ mọ? Boya e tun ranti emi papa mọ? Emi ni eni na to ma duro niwaju Ọlọrun Olodumare eni ni eni a ri ati eni aimọ to ngbe larin ọ m ọ enia, mo ni ese mefa ọwọ meta oju merun meji wa niwaju ori mi meji wa ni ipakọ mi ọkan mi, ọkan nla wa ni atari mi, Eyi lo mu mi ri ibi gbogbo.

Ọwọ mi mẹta lo ntọ ka si awọn aṣẹ ọ m ọ enia. Awon ese mefa ti mo ni wa bayi pe kin ma fi meji duro niwaju Olọrun, meji wa lati ma fi rin l a r i n awọn oku ati lati ma fi yi awọn eni aidi bajẹ, Bayi ni mo nlo awọn ẹsẹ mẹfẹfa wọnyi.

Ko si alaye to ti m ti ko ti di ok fun eyi ti a fi npe mi ni Ẹfufu Lẹlẹ eyi to nru gbi oku ti o ni ewe ko gbogbo ti awọn alaye ti fa si iho imu w ọ n nipa eyi ti gbogbo w ọ n fi wa laye

N woyi ọdun to koja mo sọ fun nyin pe awọn alaghara ti ko ba mọ mi Emi Ẹfufu Lẹlẹ yio sọ won di eni alaiẹ. Ati emi Olokiki ti ko ba mọ ọrọ Ọlọrun, emi y o sọ di eni igbagbe larin ọmọ enia.

Ati eniti o ba ro pe on tobi, emi yio so di eni Irẹlẹ Ẹ ranti eyi to ṣẹlẹ na bi? Mo sọ fun nyin ọjọ na pe emi ki iṣe W o l i, sugbọn ohunti yio ṣẹlẹ ni opin ọjọ wa ni vaju mi lati sọ f u n Ologbọn to moye

Ati ran Emi Ẹfufu i s ẹ l ẹ sọdọ awọn alaṣẹ Orile-ede yi lati tua ọna wọn se ṣugbọn ọ p ọ n gbigbọ ṣe aigbọ oireti pe a w n ṣe oh a rere.

Oluwa tun ran mi wa si lẹkan si pe, Ki awọn Ọlọla lọ ṣe iranja awọn e i ipo I ele. Emi Ẹfufu Lẹlẹ tun bere lọwọ ẹnyin ọmọ enia Kini o ieki ati ma wa Iṣare awọn woli to t ku k ja? K i e eli ati m wa oku larin awọn alaye?

Ọlọrun ran mi si nyin pe ẹlu t ju awon akuṣe awọn ti ko nireti pe wọn le wa la ye mọ fun iṣe arin wahala aiye won, Ọlọrun ran mi si nyin pe! se ikẹ awọn ota si ti ojo rẹ lori ile aiye ku tẹlẹ Ọlọrun s pe lọ ṣe ten ju awọn ọdi ọwọ mi wọnyi

Emi Ẹfufu Lẹlẹ tun sọ fun enyin Iasiwaju Ọlọrun yio s k n kikoro fun ip n ju eyi, nyin yio ma saie k ri iwaju ojiji nyin bi ọ i pe awọn ọpọ ọmọ ogun le nyin k ri niju pẹpa oko

Kini ṣe ti awọn ẹlomiran fi hu iwa ibajẹ bi ẹnipe Ọlọrun ko ri wọn Emi Ẹfufu Lẹlẹ ri ohun gbogbo mo si k gbogbo iṣẹ nyin sinu iwe iranti a wau Ọlọrun

Maṣe r pe chun kan wa tiao bo mọlẹ niwaju Oluwa Emi Ẹfufu Lẹlẹ ranṣẹ Eni watan k i f a von Ọba orilẹ ede yi ki won lọ mọ iwon ara won Nitori Emi Ẹfufu Lẹlẹ ni o fun gbogbo awọn to wa nipo iranṣẹ to ro pe Olọrun ni awọn ṣe

Inu ni afi nyin ṣe ki ẹe ori iru ni a fi olu esinṣin koro lara ki ṣe ori Ẹ l ro nu lori awọn ikilọ wọnyi

Emi Ẹfufu Lẹlẹ nrele ọ a re bọ

# Bişọbu Kalẹ Kan Saara Si Ijọba Ologun

EKO:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa ni owuro ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi nifi Bisobu ti Ijọ awọn C. M. S. ti ilu Eko Eni Qwọ S. I. kalẹ ti kesi gbogbo olugbe ile Naijiria lati ni iṣọwọpọ pẹlu Ijọba Ologun ilẹ Naijiria lati le tete jẹki eto alafia ati Ijọba rere le fi ẹsẹ malẹ ni orilẹ ede Naijiria.



Ẹni-Qwọ Kalẹ

Ninu ọrọ Ẹni-Qwọ S. I. kalẹ ninu ọrọ ti o sọ eyiti ọ fi ṣe alaye pe on fi ara mọ eto akoso Ijọba Ologun ilẹ Naijiria.

Ẹni-Qwọ kalẹ tun ṣe alaye siwaju si pe ọpọlọpọ enia ni okan to sọlẹ ni ori ẹede Naijiria laipẹ yi yio lẹnu ati pe bakanna ni yio jẹ iyalẹnu fun ọpọlọpọ enia pe nwọn ko mọ pe orilẹ ede yi le ni iṣọkan ailẹ bayi eyiti iṣe iṣẹ ọwọ Ijọba Ologun ile Naijiria. Bişọbu Kalẹ tun ṣe alaye pe ọpọlọpọ enia ni yio ma sọ wipe bawo ni Olori Ijọba Ologun yio tise ma sọ pe awọn fara mọ eto akoso Ijọba Ologun.

Ẹni-Qwọ S. I. Kalẹ tun se alaye pe ohunti Ijọba Ologun orilẹ ede Naijiria se yi si jẹ ohun ti o se pataki pupọ lati tet ri pe gbogbo rudurudu ati aisi Ifọkanbalẹ te wa si ipinlẹ Iwọ Orun tẹlẹ tun lọ si opin ati paapa nlọ ni orilẹ ede Naijiria bayi.

Ẹni-Qwọ Kalẹ tun se alaye pe ohunti awọn Olori Ijọ ile Ọlọrun ni lati se bayi ni pe ki nwọn mase da ọwọ adura duro ki nwọn si ri pe apa ẹṣẹ adura nwọn gba gbogbo ohunti o nsẹlẹ ni orilẹ ede yi kuro.

O tun ṣe alaye pe adura ti o tun ṣe pataki ti awọn Olori Ijọ ile Ọlọrun yio mase ainiye ni eto akanṣe adura fun awọn Olori ilẹ na bayi eyiti iṣe awọn Gomina Ologun ni orilẹ ede yi ati awọn ọmọ Ogun to wa fun lati ri pe nwọn se eto ti nwọn yio se nipa ilẹ Naijiria yi lọna to tọ ati eyiti o yẹ lati leri pe pẹlu ibukun Ọlọrun ni nwọn fi lẹ gbogbo awọn eto na.

Ẹni-Qwọ S. I. Kalẹ tun ṣe alaye pe ohunti gbogbo enia orilẹ ede Naijiria yio se bayi ni pe ki nwọn ri mọ pe olukuluku Olugbe ilẹ Naijiria ni iṣọwọpọ pẹlu eto akoso Ijọba Ologun ilẹ Naijiria lati le tete da eto alafia Ijọba rere ati ibukun si orilẹ ede Naijiria.

Bisọbu Kalẹ tun se alaye ohun ti o jẹ pataki ti awọn Olori Ijọ ile Ọlọrun yio se bayi ni ki wọn ma se eto ilẹ ọna lati awọn enia orilẹ ede yi lati le yi ọkan enu ati iwa buburu kuro lọkan wọn.

O tun ṣe alaye pe bayi pe awọn enia ilẹ Naijiria ati awọn Olori ilẹ na ni ọmọ iṣọkan ati pe ki nwọn si ni ifẹ rere ati awọn iwa ti ko ba oju mu, o ni ko si ohunti nwọn le se ni orilẹ ede Naijiria nipa eto ti o ti wa ilẹ nipa eto ofin rere, awọn ipinlẹ ti wọn yio tun se ati pe nipa awọn ohun miran ti nwọn yio se ni o ṣe alaye pe kale yori si rere bi ko pe nwọn se gbogbo ọna ọtọ bi o ti yẹ.

Ninu ipari ọrọ rẹ Bisobu Kalẹ tun se alaye pe nigbati asiko nawẹ iṣẹ ti o de o ni olukuluku ni o ni lati kun fun adura lati le fi pa gbogbo ẹṣẹ ti o wa ni orilẹ ede Naijiria rẹ ati pe lati le mu gbogbo ẹṣẹ eyiti ijọba to ti nse eto akoso ti ilẹ ede iṣẹ ti da silẹ ati pe eto Ijọba rere ni ẹṣẹ mulẹ nigbati Ijọba Ologun to nṣẹ gba akoso Ijọba na yio silẹ lati le jẹki awọn enia ti yio se akoso Ijọba na lọna otitọ ati ododo le gba Ijọba na.

---


# Kere o

Bleyi ni lati fi kede fun gbogbo ẹnyin Musulumi ododo pe Kurani ọlọgọta esu ati itumọ rẹ ti de nisisiyi fun tita ponun kan abọ ni eyọ kan (£1 10)

Gbogbo awọn oro ninu Iwe mimọ na ni o han kedere

Wa ra ni Ṣọbu:—

C3/64 Abẹokuta Motor Road

*tabi*

Ki O kọwe si

ALUFA SIKIRU
BOX 4 AGEGE


---


# WANTED

Apprentice Printers And Advanced Apprentice Compositors
Apply in person to the;

MANAGER

16 Bamgbose Srteet,
LAGOS



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO NIPA **DYNAMIR** TỌNIKI



ALE-IBI-ALE Egbogi Tọki amọnu, titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ ... Agbara ati Aṣẹbidan ṣẹ I ra agbalagba Ọkunrin ati Obinrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun dada de ọkan lọsan tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Emi Breath ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi nu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti koja ọgbọn ọdun si adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di ọtun ... pata oju rẹ yio si walẹ re kete alafia ati igbadun de Bere Dynamiren yi ni Ṣọbu awọn :-

Waterloo Medecine Stores
8. Palm Church Street P. O Box 333 Lagos
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos
ADEDUN CHEMIT
14, Wakeman Street
ATI NI ṢỌBU
IṢB OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN


---


**The NEW HOOVER**
Washing Machine
Makes Clothes
Whiter and Brighter
It's easier the....
**HOOVER** way

The NEW HOOVEMATIC washes ... rinses ... spins dry 6lbs. of clothes in 8 minutes all in one continuous operation. That's the amazing performance of the new Hoovermatic, a combined Washing Machine and Spin Dryer.



AVAILABLE AT
LEVENTIS TECHNICAL
MARINA — IDDO — IBADAN—
KADUNA — JOS — KANO—
P. HARCOURT — ABA
and Kingsway Stores.

## Gomina Ologun Fajuyi Gbodo ko Oro Aponle

IKARO—IFỌN: Awọn ọmọ ẹgbẹ ẹgbẹ Ikamarun ni nwon ti kesi Gomina Ologun F A F juyi ti Ipinlẹ Iwo Orun pe ki o ma a se feti si ọro asodun aponle ati ete ọtan ti awọn ẹgbe oselu kan nfi ranṣẹ si i lori ipo nla ti o bọ ati inu osu ti o koja, nwọn ni ki o maa ṣe gba oro na gbo ki o tun gbon o nkan ti Ijọba awon le kuro nibe ti ba ẹ ṣe daradara ki o to fi Ijoba na le awon yio mo se lowo.

Ninu ọro ti akowe ẹgbẹ na Ọgbẹni J O Orika kọ, ranṣẹ si Iroyin wa ni ibẹrẹ osẹ yi ni o tise alaye pe. Awa ti a jẹ omo ẹgbẹ ẹgbe Ikamarun osuro loru o ra wa pe inu wa dun fun igbe ṣe rere ti Gomina Ologun Ipinlẹ Iwo Orun gbe lati dabobo ere ofẹ awon olu gbe Ipinlẹ Iwo Orun.

O tun pe ti a tunkesi Gomina ti o wa tẹlẹ ti fun wa ni ẹro omi ati ina manamana ati awon nkan meremere miran a ko gbọ nlọ nbọ mọ titi di gba ti Ologun gba gbogbo Ijọba ilẹ Naijiria.

Ninu airi kanṣekan ni a wa a n se gbara wa lati fa ramọ Ijọba ti o ba wa ni ori arẹ ri gbogbo wahala wa ti a nṣe a ki ri ire kan kan nibẹ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na ti ke si ẹro omi ti nwọn si fun wa lati maa lo ni awọn ilu Odo, Akurẹ, Owena, Ifẹ ati Gbongan.

A fi ara mọ aturse ti Ọlọrun ran si wa nipa gbigba ti awon omo Ologun Apa pọ Ijọba orilẹ ede yi nwọn jari ọrọ nwọn pe ki Gomina Ologun na maa gbagbe agbegbe Ikamarun fun ohun meremere.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Ọpọlọpọ nkan iyanu ni iwọ yio ri loni, ṣugbọn ki o ma gbaradi fun ohunkohun ti o le de, awọn iṣe ti o jẹ pataki ni ki o kọkọ yan ju bi o ba ti de ibi iṣẹ, lowurọ yi.

PISCES (Feb 21 Mar 20) Sugbọn loni, alafia yio to ara tonẹ ti o jẹ wipe gbogbo iṣẹ ti iwọ ko ti ṣe ri ni iwọ yio ma ṣe. iwo yio se awọn iṣẹ na ni aṣeyọri kedere.

ARIES (Mar 21 April 20) Irọrun ni gbogbo ọjọ oni yio jẹ fun o, ohun gbogbo ti o ba si ṣe yio mu tẹ o lọrun, mura ki o tun ara rẹ ṣe, fun ilọsiwaju. nipa ohun ti o ngbero ninu ọkan rẹ.

TAURUS (April 21 May 20) Maṣe fi ara silẹ fun aarẹ ti o fẹ yọ o lẹnu ki o si ni ọgbọn ninu nitori ọnikan nibẹ ti yio maṣe lara rẹ si ma fura si o oyi dara pupọ.

GEMINI (May 21 June 21) Ọpọlọpọ ohun ti o jẹ iṣoro fun ọ ni iwọ yio le yanju patapata ti yiori fun ọ ni itẹlọrun iwọ yio si gburo ọrọ kan lati ọdọ ajoji enia kan.

CANCER (June 22 July 22) Iwọ yio mọ ni ara rẹ wipe a ti gbe ẹru nla kan kuro ni ejika rẹ. tobẹ ti ara rẹ yio ya lati ṣe iṣẹ kiṣẹ.

LEO (July 23 Aug 22 Ijọngbọn kan si mbẹ nilẹ ti o nfẹ amojuto ni owurọ yi, ṣugbọn ki o maṣe kọ ibi ara si nitoripe ti ola ni yio ṣoro. maṣe ti lo gbogbo ọgbọn ori rẹ silẹ tan.

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ire yio kan ọ lara ni owurọ yi, ṣugbọn nigbati osan yio ba fi pọn, aarẹ le de si ọ, ohunkohun ti o ba si lo si, alafia yio de.

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Ire mbẹ repẹtẹ loni, ti yio si te lọrun pe ọkan rẹ bakanna ni yio ti ni akoko, sa ṣe jẹjẹ nibi iṣẹ rẹ ki o si jẹki ero ori rẹ pe.

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Ire mbẹ fun ọrọ abẹ ile iṣẹ loni, mura ki o si ma ṣe itọju ipalẹmọ ọdun Keresimesi ki o si ran pe awọn enia ti yio wa ba o ṣe ayẹyẹ na, we ni ki o kọ si wọn.

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Dupẹ fun oṣupa rẹ ti o nta ni ingiẹ alafia yio to ọ lọwọ o kosi ni ri ikọlu buruku, lọdọ awọn ọrẹ rẹ ni ki o lo gbogbo nkan yio fi tẹ ọ lọrun.


## Ha Kini Eleyi




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara jul gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun,

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si danwo; iwọ yio ri bi o tiṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu ori erin mẹta ni nwọn mu fun ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ile itaja kakiri orilẹ ede yi

Distributor
AMOS GBENLE & BROTHERS
34: Docemo Street Lagos
6 & 11 Balogun Street West



# E Ma Ka Iwe Irohin Imọlẹ



# KERE O

Njẹ o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA to ṣẹṣẹ jade?

Ha! Kosemani ni iwe na jẹ fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan iṣẹdalẹ Yoruba. Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Maṣe jẹki nwọn rohin itan ilu rẹ fun ọ
3/- pere ni. Postage 9d

Tete f'owo tirẹ ranṣẹ si:-
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria

# Ina Sọ Egbẹrun Ẹnia Di Alaini'le

ABAKALIKI:— Oro di bi o ko lọ o ya fun mi ni ọjọ ọjọ 'Bọ ti işe ọjọ keta oşu yi nigbati ijamba ina nla kan şelẹ ni abuleko kan ti nwọn npe ni oko Iboko ni ekun Abakaliki Ipinlẹ Ila Orun Naijiria eyiti o je wipe ọlomọ berisi gbomọ pọn nigbati ina nla na şẹlẹ ninu ilu na ti awọn enia ti nwọn to ẹgbẹrun di alaini'le ati pe awọn dukia awọn enia ti ina na jo ile wọn ti o şegbe sinu ina nla na si to ẹdẹgbaji pọnun (£15,000)

Onlwe irohin wa ni ilu Abakaliki to lọ sibi ti ijamba ina nla na ti şẹlẹ fi ye wa ninu irohin rẹ pe şẹlẹ ina nla na şele ni oru oganjọ nigbati gbogbo awọn enia to ngbe ni abuleko na ti sun lọ eyiti o jẹ pe airotẹlẹ ni ina na ba gbo gbo awọn enia abuleko na.

N na oro eniti işẹlẹ na şe oju re fun O lwe ir hin wa ni o ti şe ala e pe ina nla to şelẹ ni ilu na fi jo gbo awọn ije ilu na eyiti o je pe opolopo awọn ohun Ọsin ti awọn enia ilu na nsin awọn oh in Osin bi Ewurẹ, Adie, Aja ati awọn opun jije miran ti Isu, epo pupa ekuru ati gari ni gbo gbegbo re si se'gbe sinu ina na eyiti irohin na tun fi ye wa pe ko si nkankan to ku silẹ ti Ina na ko jo rau-rau.

Onirohin wa fi ye wa pe o koti le sọ boya enia ku sinu Ina na ati pe awọn enia ti ọbogbo won si to ẹgbẹrun lo jẹ pe awọn jade kuro ninu ile won laifi ara gbogbe ka kan ninu ina to şelẹ ni abuleko na

Onlwe irohin wa fi ye wa pe ninu awọn ẹgbẹrun enia ti ina na sodi alaini'le gbe ni a gbọ pe ninu awọn ile ọ oni ilu b k liki ni won ng e l ti le dabo bo ara won ninu ile ẹko na

Şugbọn a ko ti mọ ohun to fa ijamba ina nla na wa, şugbọn awọn ol pa ti bẹrẹ si şe Iwadi ohun to fa ijamba ina na lọ wa

# WANTED

Apprentice Printers And Advanced Apprentice Compositors
Apply in person to the;

MANAGER
16 Bamgbose Street,
LAGOS

# Iwe Itaja 1966

Idamu owo ha wa fun ọ bi
Abiku ha nyọ ọ lẹnu bi
Ariṣẹ se ha wa fun ọ bi
Ailera mba ọ jà bi

?

Iwọ le bọ ninu gbogbo wahala aiye wonyi ti i o ba ra ninu awọn ohun Ijinlẹ işẹdalẹ Yoruba ti a to lẹsẹsẹ si Isalẹ yi.

1 Iwe Egbogi Aiẹbidan 25/— di 22/6
2 Iwe Afọşẹ Işẹdalẹ Yoruba ati Psalm Aiẹbidan 4/6 di 3/6
3 Iwe itumọ Ala ati Ogun Wabẹiẹbẹ 4 6 di 3/6
4 Iwe Egbogi Awogba Arun 20/— di 17/6
5 Iwe Ilana Ifa Yanrin tite ati ẹrọta yiyẹ 20/- di 17/6
6 Gbedegbeyọ Hausa 3/—
7 Iwe Yoruba Iron 2/— di 1/—
8 Turari Legun Ajẹ ati Itaja 10/6 Pangolo 2/6 paketi

Fi Owo ranşe si

J. O. SAOYINKA
P. O. Box 159
MUSHIN

tabi

9, Iyala Street Odusbgre, Mushin

BERE FUN OJULOWO EGBOGI—

# "Congreve's Iodo Form—Ointment"



Atamatase ni egbogi "ADI-ELEGBO" yi fun itọju egbo egbo ori,irişi "EGBO—EṢẸ" ni kiakia bi o ti wu ki o ro ti le pẹ to, Adieegbo yi ki ni ẹgbẹ nipa wipe awọn ko dọti ni bi ẹni gẹ ogbo ti ba wa loju egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo yio bajẹ si yio jinlẹ oju re hu wa soke, yio si pọn daradara tun bakanna ko si mo werewere ni yio si san patapata Alafia de si ọ niyen :—

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si sale iwe yi ni egbe ranşe lọ ra. Bibeko awọn Eleru abi onijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maşe gba rara o

Waterloo Medicine Stores
8 PalmChurch Street Lagos
22878 Lagos Nigeria (Ọja Faaji)
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos
NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street Lagos

a successful future

means planning Now!

Have you planned for the security of your family's future? Start a programme of Life Insurance NOW

with

GREAT NIGERIA INSURANCE Co. Ltd.,
(INCORPORATED IN NIGERIA)

Enquire now for full details of our low cost endowment policy.

HEAD OFFICE:

39/41 MARTINS STREET,
P.O. Box 2314, LAGOS
TELEPHONE 25251.

BRANCHES AND AGENTS THROUGHOUT NIGERIA.

# E Ma Ka Iwe Irohin Imọlẹ

